Akiyesi

Anfe Enati yio ma wa ta Iwe Irohin Imole Ni agbegbe Ilorintabi Ilumiran. E kowe si odo Ogbeni: R. O. Adedeji Esq Ni P. O. Box 12 Ilorin

IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA.

AKIYESI

E ma polowo oja yin sinu Irohin Imole

VOL. III No. 140 MONDAY MARCH 7 — MARCH 13 1960 KOBO KAN (1d)

# Ha! Oyinbo Obinrin eni odun metadiladota jale ni sobu Kingsway ni Eko

ISABELA HISLOP OYINBO-BINRIN TI O JE ENI ODUN METADIN-LADOTA NI A GBO IROHIN PE " O JALE NI SOBU KINGSWAY. OHUN TI A GBO PE O JI NI IGO ICE CREM KAN ATI PANU ERAN CORNED BEEF K A N " TI OWO WON JE SILE MOKANLA ATI KOBO MEJI.

Nigbati ejo re bere ni Ile ejo l'Eko ni ojo Jimoh ose tokoja, Isabella so fun I l e E j o pe on gbagbe gbogbo ohun ti on ko sinu A p o on ni, ki o to di wipe enikan wa ba on, pe on Ja-le.

O so fun adajo pe on duro ni enu ona sobu Kingsway ni opopo Martins Street, ki o to di wipe okan ninu awon ti o nso sobu to wa rin to on, fi o si so wipe on ji awon eru ti o wa ninu apo iraja ti on gbe sowo ati pe on ko lati sanwo awon oja na.

O tun fi nye ile ejo wipe lesekese ti on gbo oro yi, nise ni enu ya on, on ko de le so nkankan. Nigbana ni won wa mu on lo sinu iyara ise oga Kingsway, ni won wa so wipe ole ni on, awon yio si pe Olopa. O ni teleteie ri ni ojo ti nkan yi sele, on ti lo si iyara to tutu (Cold Store) lati raja, on de ra pali Wara (Milk) kan Ori Amo (Butter) kan pelu Cheese ati Buredi. Lehinna ni on tun ra Beer ati Ice Cream ti on si ko gbogbo re sinu apo iraja on.

O ni nibi igbowo on s a n gbogbo owo oja ti on ra sugbon on gbagbe lati san o w o Ice Cream pelu eran Corned Beef, o wa se afikun w i p e ka'ni on ko awon eru ti on ko san owo fun wonyi, fi on ba de i l e on o ba pada lo lo san owo awon oja na ni ojo ti on ba de Kingsway.

Ninu ejo yi Agbejoro Odaran Oyinbo-binrin yi dide o si so wipe Odaran na ti fun on ni ase lati san sile-mokanla ati kobo meji owo oja ti won ni on ji, Agbejoro na si san owo na.

Nigbati Agbejoro Ijoba bi Odaran yi lere oro kan, o dahun o si wipe on gbagbe lati san owo oja na ni.

Ile Ejo wa fi gbigbo iyoku ejo na si ojo Jimoh lose yi. Bi aba ti ngbo bi ejo na ti nlo si, e o ma gbo.

## Oga Bank tun ji owo Ogorun Poun

ADEOYE OSHIBANWO O g a Ile Ifowo-pamo si ti Agbon Magbe Bank ni Irohin deti igbo wa pe oji

WO IYOKU NI OJU EWE KERIN

Ha! eti re melo?



Eyi yi ni Ero Alata to dara ju gbogbo eyi ti won ti nlo tele ri lo, lehin ata lilo, o tun le lo Igbado ati Oka-Baba, at Ewa ere orisirisi.

£45 ni a nta Pelu Enjinni Petrol tabi ati pelu Eletiriki Muto.

O WA NI SOBU

Akoshile Brothers

5, Balogun Street West,
P. O. Box 599
Phone No. 24395. Lagos.

MOGBAYI BABY MIXTURE

OLURANLOWO FUN AWON ABIYAMO

MOGBAYI BABY MIXTURE je ogun pa taki ta se ni Asepe fun Awon omode, ati olo ogun yi fun opolopo odun sehin pelu idaniloju fun Awon ise ribiribi ti o ti nse. MOGBAYI BABY MIXTURE je egbogi to dara pupo fun igbona iko, otutu Aiperi, Osi inu omode, jedi j e d i Kokoro ori omode. O dara fun omode ti ko tete rin ati fun awon aisan miran bebe lo. O nmu ki omode ma nsun fonfon, o nmu ki ehin bibu je iro run fun awon omode. osi njeki awon omode tobi, osi nmu won dan ni awo. Enyin Abiyamo, eku afojuba egbogi yi. Aran yin leti pe MOGBAYI BABY MIXTURE je egbogi ti kose mani fun awon omode. Ijafara lewu pupo, tete lo ra ti e ni ile itaja Egbogi towa ni Adugbo re.




Igo kekere re je 2/6d Igo nla je 4/6d

LILO RE:- Sibi kekere kan lemeta lojumo

*Wholesale Distributors*

A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHERS

6, Balogun Street West Lagos Nigeria. Phone 22515

34, Docemo Street Lagos Phone 24247

**IMOLE**

ESIN ORO WA
IMOLE DE OKUNKUN PARADA
Editorial Works & Office
16, Bangbose Street, Lagos
Telephone:- 21985
United Kingdom Representative
Publishing Distributing
177, Regent Street,

# ONJE ILERA TITUN FUN ILE NAIJIRIA

## Glaxo se iranlowo lati wo Ailera Omode

ONJE ILERA TITUN KAN TI A NPE NI "AMAMA" WA NI TITA NI NAIJIRIA NISISIYI LATI DOJU IJA KO IKU OMODE TI O PO NI NAIJIRIA, EYI TI AIJE ONJE TI O FUN NI ILERA NFA. ONJE YI JE IYEFUN PUPA KAN EYI TI A LE PO MO ONJE OMODE; O KUN FUN EPA LILO TI ATI PO MO IWUKARA (YEAST), WARA, IYO OYINBO ATI OPOLOPO OHUN TI O NMU ILERA WA.

Ile-Ogun Glaxo (Nigeria Ltd) ni Apapa ni ati nse Amama. Omo osu mefa titi de omo ile iwe ni won saba ma nni arun ekunra nitori aije onje atata. Arun ekunra je arun ti iete wo omode lara, a ma nii lara o si npa opolopo. Ti o ba wo omo lara tan o soro la ti wo nitoripe ki ise pe aisan yi yio da omode lama nikan, sugbon ko ni je ki onje wu won je.

Nitori idi pataki meji wonyi, o pataki pe ki aw ona bi arun yi ko se ni ba omode ja rara. Bi aisan na ko ba ni ba omode ja, omo na nilati je onje ti yio fun u ni ilera tabi ki a po Amama mo onje re. (Amama kun fun onje ti o pe.) Bi a ba po Amama mo onje omode nigbagbogbo ko ni je ki arun buburu yi ki o se e.

Awon Onise-iwosan ni Naijria se ajumoro nipa aisan yi ninu Ipade Onjeiwosan ni Ibadan ni osu kesan odun 1957 nigbati a fihan pe onje ilera, ti ise atunrase ni kikun ko ni kikun, ko si ninu onje opolopo ni iha isale Naijiria nibiti o je pe isu ati gbaguda ni onje won poju. Ni apa ibomiran papa onje ti imu oniruru eya ara sise won bi o ti to sowon.

Ni 1955 Onisegun W. F. J. Cuthbertson, olori ise onje Glaxo ni Greenford England nigbati o nsise ni Ile-Eko giga (University College) ni Ibadan ri opolopo idamu ti aisi ohun atunrase ninu onje nfa wa fun awon omo iwo Orun Afrika. Nigbati o pada si Londonu, on ti awon osise re bere si wadi onje nikun ti o ntun ara se, ti o si ni mu ilera ba [illegible], ti a le fi opa se pataki re.

Lehin odun meji, Onisegun T. F. Macrae, Oga Eleto Glaxo, lo opolopo irin-ajo ni Afrika lati ba awon Onise iwosan ni Afrika ti nsise ni Ile wosan, Ile-ibimo, ileto ati Ile-iwadi Ogun soro ati lati gbo alaye won nipa aisi onje ilera, ati atunrase ninu onje. A fi tijotayo gba a l'alejo ni ibi wonyi ko si le gbagbe iru iha ti awon onise itoju awon omode ko si Eto Glaxo ti o fun 'ni ni isiri pupo.

Amama dara lati fun omode pelu onje re ni ekun-sibi Glaxo merin lojojumo (1-oz) Pipo onje ni titi omo yio fi pe odun mefa tabi meje. Glaxo pinnu lati je ki rira re rorun fun awon ti o fe lati ra Amama fun omo won Pali Amama, ti o kun fun sibi mejil-elogbon fun lilo ojo mejo, je sile-kanabo (1/-6d) pere, eyi ti olukuluku enia le fi irorun ra.

Lati ko awon enia ni lilo re ati lati polowo re, opolopo moto ni a gbe fun awon enia Afrika, ti a ti ko jafafa ni ise ipolowo oja, ti o nkakiri Naijiria lati mu irohin yi ba gbogbo enia. Teletele, ni awon agbegbe wonyi, awon enia ti gbo irohin Amama dunti nitori ni aimoye Ile-iwosan ni ati ndan a wo ti a si njeri pe o dara. Awon moto wonyi lo akiri opolopo ilu ati ileto ti awon nlo o bi o ti ye ki a lo o han awon enia, Pelu gbogbo iwonyi a se Sinima Amama, ti o jepe kiki ara Naijiria ni o se e, ti a fi nhan awon enia ni gbogbo Ile Sinima ni Naijiria; a si te oniruru iwe Akiyesi nlanla ti a le mo oja ati opolopo Ileto. Lati odunmodun ni aisan ekunra omode ti npa opolopo omode papa lanin awon ti ngbe ile Yoruba. Pipa ti o npa won bayi, idamu ati irora awon ti a kolu ti ko se fi enu so inu ki o je olori isoro fun awon Onitoju Omode ni Naijiria.

# E fun Awon Olugbe Surulere ni Ina Lentiriki ti Opopo ona

TI A BA DASO FUN OLE, PIPA LA NPA NI ARO FUN.

Gbogbo Olugbe ti o ti mbe ni ilu Eko ni won ti di ara Suru-Lere, sugbon Ijoba ko se elo fun won bi o ti to, ati bi o ti ye. Oja ko si fun won. omi ko si gegebi o ti ye ki o wa. Eyi ti o tun wa buru ju ninu re ni INA ELENTIRIKI ti Opopo ona (Street Light). O je ohun ti o ba Suru-Lere je gidigidi, ti ko ba se asiko Osupa, enikeni ko le gbadun Surulere gegebi Olugbe, eyi si je ohun ti o buruju. Nitorina awa eniwe Irohin Imole fi tokantokan be awon Ijoba lati mu oju to ti INA LENTIRIKI yi, lati fi se opopo ona Surulere gbogbo loso papajulo Opopo Olajuwon titi de Tejuosho yo si opopo Western Avenue ni oruko gbogbo awon Olugbe agbegbe ibi ti a daruko wonyi, a be nyin gidigidi lati se oju ise yin gegebi Ijoba, nitori ohun ti a ba da owo le, asetan lase. Ni ibi meji ti a da oruko nwonyi ni Opopo Ina wa, sugbon ko si ina nibe rara.

Lakotan ara bakanna ni opopo ITIRE egbe ina Itire de ibikan esi fi sile lai ko fi owo kan sugbon gbogbo ile ti owa nibe ni o ni INA LENTIRIKI ni ile. eyi si fi han dajudaju pe Iwa ko si enikan yio mu wa ni agunla ti ijoba se nipa ina ti Opopo, iru re iwa bayi je ni o ma mu opolopo enia rewesi nigbati oro ILU ba sele, ti enyin MINISITA ba nwo ojule kakiri wipe ki nwon dibo fun, eo si ma ko bi Iya Ajigbo ti e ba wole, eo wi awon ti o dibo fun nyin sinu. Eyi ko dara rara.



## ITUMO Ala awon Onibere

Timothy Osunkẹyẹ Oko Baba Ebute Metta- Sọra gidigidi ni asiko yi, koma ba Kagbako buburu, awọn aiye nlepa rẹ kikankikan lati gba ẹmi rẹ ṣugbọn ti o ba nṣọra rẹ lasiko yi ọwọ ko ni tẹ ọ. Igbọran lẹbọ, ma si ṣe finu han enia rara.

Bere ala rẹ lọwọ:-
Joseph alala.
6, Ojo Road ( Oduabọrẹ )Mushin

Akiyesi:- O le ri Iwe ala ati Odu Ifa ra ni ọdọ wa 2/6 pere ni, tete wa ra tirẹ ki o to tan.

## Imoran Nipa Ife larin Okunrin Ati Obinrin

BOSẸDE/ O di ọdun meje gbako ti mo ti fẹ Obinrin kan, nigbagbo ti a ba nsọrọ ni o ma nsọ pe on ko ni ifẹ mi rara awọn ẹgbọn on lo jẹki on fẹ mi atipe Ọkọ ti on kọ silẹ, enia lile ni eyi ni o tubo mu ki awọn ẹgbọn panupọ pe ki on kọ ọ silẹ pe dandandan emi ni on ni lati fẹ atipe ki se ifẹ inu on. Igbakugba ni a si ma nja ti o si nko lọ si ile wọn. Oti bimọ meji fun ọkọ akọkọ, Bosẹde ko si igbati a le ja ti ko ni ma fẹnu mọ pe on ko ni ifẹ mi lọkan ko si ti bi ọmọ fun mi o. Ọrọ yi nbami lokan jẹ kini ki nṣe o?- Alubarikalolu Bros Lagos.

## Imoran

ALUBARIKALOJU BROS LAGOS/ Mo gbọ ọrọ rẹ ni agbọyekeyekeyeke, kini yi mo fẹ ṣe, yatọ si dandan o ni lati ṣee. ohunkohun ti a ba fi agbara mu ṣe, ṣe lai ṣe ifẹ inu re igbẹhin rẹ ki dara mo gba ọ ni iyanju pe ki o ṣe giri bi ọkunrin, moju kuro lara obinrin yi nitoripe ohun ti o wa lọkan rẹ ni o nsọ fun ọ yẹn tete kọ silẹ ki ọkan rẹ bale fuyẹ nitotọ

Emi ni Bosẹde
6, Ojo road, Oduabọrẹ
Mushin







